# “Ẹni ti o ba lọ ba yẹmiwo kan ti o wa bi i leere nipa nnkan kan, wọn ko nii gba irun rẹ fun ogoji ọjọ”

Lati ọdọ àwọn kan ninu awọn ìyàwó Anọbi- ki ikẹ Ọlọhun ati ọla Rẹ maa ba a- lati ọdọ Anọbi- ki ikẹ Ọlọhun ati ọla Rẹ maa ba a- o sọ pe: “Ẹni ti o ba lọ ba yẹmiwo kan ti o wa bi i leere nipa nnkan kan, wọn ko nii gba irun rẹ fun ogoji ọjọ”.
[O ni alaafia] [Muslim gba a wa]

Anọbi- ki ikẹ Ọlọhun ati ọla Rẹ maa ba a- n ṣọ wa lara kuro nibi lílọ bá adagbigba- orúkọ kan ni ti o kárí fun yẹmiwo, ati awòràwọ̀, ati ẹni ti n tẹ yanrìn, ati bẹẹ bẹẹ lọ, ninu awọn ti maa n mu ẹri wa fun mímọ kọ̀kọ̀ pẹ̀lú àwọn itisiwaju kan ti o maa n lò- ati pe ọ̀wọ́ọ pe èèyàn kan bi i leere nipa nǹkan kan ninu kọ̀kọ̀, Ọlọhun ko nii fun un ni ẹsan ìrun rẹ fun ogójì ọjọ́; ki ìyẹn le maa jẹ ìyà fun un lórí ẹṣẹ ńlá yìí.

https://sunnah.global/hadeeth/yo/show/5986